# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸ́LẸ̀

## ÒFIN ỌBA NÁÀ

## Ìtàn ...

**Danieli 6:1-28**

Lẹ́yin ìgbàtí Dariusi Ọba Media ati Persia ti ségun Babiloni, ó pa gbogbo àwọn ìjòyè ìjoba Babiloni, Ó sì sẹ́ ọ̀kan kù sílẹ̀. Ọkunrin kan tí o sẹ́kù náà ni Danieli, ìránsẹ́ Ọlọrun òtítọ́. Lati aadọrin ọdún sẹ́hìn li ati kó o lí ìgbékùn lati Juda lọ sí Babiloni, a sì yàn án láti má a se ìránsẹ́ li ààfin gẹ́gẹ́ bi I olùgbàmọ̀ràn fun ọba Babiloni. A si mọ Danieli yíká gbogbo ìjọba náà wípé ó ní 'ẹ̀mí títayọ'. Danieli 5:12; 6:3.

Kí i sì se wípé Ọba Dariusi dá Danieli sí nìkan, sùgbọ́n 'Ó rò láti tún gbé e ka orí ìjọba'. Danieli 6:3. Nígbàtí àwọn ìjòyè Medo-Persia sì ti mọ wípé, Ọba fẹ́ gbé e ga, kí o le e jẹ́ alásẹ lórí wọn, wọn bẹ̀ẹ̀rẹ̀ sí í jowú ati lati máa korira rẹ̀. Nítórí ìdí èyí, wọn gbìmọ̀ láti kọ ìwé òfin pé kí ọba Dariusi leè fi ọwọ́ si, pé kí ẹnikẹni tí ó bá bèèrè nkan lọwọ Ọlọrun tàbí ènìyàn kéníyàn níwọn ọgbọn ọjọ́ bíkòsepé lọ́wọ́ ọba, a o gbe e sọ sínú ihò kìnìún.(Danieli 6:7). Àwọn ọkunrin wọ̀nyìí mọ̀ dájúdájú pé Danieli kìí fi ìgbé ayé àdúrà seré bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú ó gbájú mọ́ ati má a pa òfin Ọlọrun mọ́, èyí tí o lòdì sí ijọsìn sí ọlọrun míran. (Eksodu 20:3).



Gẹ́gẹ́ bí wọ́n se nretí, àwọn ìjòyè náà ká Danieli mọ́ ibi to ti ngbàdúrà sí Ọlọrun rẹ̀ láti ibi fèrèsé tí ó sí sílẹ̀. Nígbàtí ọba sì tì ri wípé, wọn ti mú Danieli, ẹni ti ise ọ̀rẹ́ rẹ̀ àtijọ́, pé yíò lọ sínú ihò kìnìún, ó sa gbogbo ipá rẹ̀ láti dá a sílẹ̀ lọ́wọ́ òfin bùburú tí ó ti fi ọwọ́ si, sùgbọ́n pàbo lí ó já sí. Lódodo Danieli lọ sínú ihò kìnìún sùgbọ́n Ọlọrun san ẹsan ododo rẹ̀ fun un nípa wípé Ó ran angẹli Rẹ̀ lati lọ dí àwọn kìnìún lẹ́nu, kí wọn ma ba pa a lára. (Danieli 6:22).

Àsọtẹ́lẹ̀ sọ fun wa wípé, li ìkẹyìn ọjọ́, àwon ènìyàn Ọlọrun yio gbe irú ìgbésẹ̀ tó jọ irú èyí lati má a wípé ọba wo ati òfin wo ni kí á pamọ́.

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

**1.** Njẹ́ òfin Ọlọrun le se e túnse tàbi pàrọ̀ bí?

**Luku 16:17**
Ṣùgbọ́n ó rọrùn fún ọ̀run oun ayé láti ______ lọ, ju kí sónsó kan ti òfin kí ó yẹ̀.

**Orin Dafidi 89:34**
Májẹ̀mú mi li èmi kì yíò ____, bẹ́ẹ̀li èmi kì yíò yí ________ tí ó ti ètè mi jáde padà.

**Orin Dafidi 111:7,8**
Òtítọ́ àti ìdájọ́ ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀; gbogbo òfin rẹ̀ li ó dánilójú, Nwọn dúró ______ ati láíláí, nínú òtítọ́ àti ìdúró-sinsin li a se wọn.

**Malaki 3:6**
Nítorí Èmi li Oluwa, Èmi kò _________, nítorí náà li a kò se run ẹ̀nyin ọmọ Jakọbu

Àkíyèsí: Kò sí bi ó ti wù kí ó rí tí a ó fi tún Òfin Mẹwa Ọlọrun ṣe tàbi kí a pàrọ̀ rẹ̀. Ó wà títí láí gẹ́gẹ́ bi Ọlọrun se wà títí láí. Ìgbà mẹta nínú Bibeli, li àwọn ọba ayé wọ̀nyí (Herodu, Ahasuwerusi, ati Dariusi) ṣe òfin tí wọ́n sì fẹ́ lati yi i padà nígbà tó ṣe díẹ̀ ṣùgbọ́n tí kò ṣe é yípadà fún wọn. Bí òfin àwon aláìlera, tí nse iyèméjì kò ba ṣe é yípadà fún wọn, báwo wa ni ẹnikan ṣe lè rò wípé Òfin ayérayé ti Ọlọrun – ti a fi ìka Rẹ̀ kọ sí orí òkuta – se lè yípadà ? Wo àwọn àfiwé tó wà laarin Ọlọrun ati Òfin Rẹ̀.

| ỌLỌRUN JẸ́ | | ÒFIN JẸ́ |
|---|---|---|
| Luku 18:9 | RERE | Romu 7:12 |
| Isaiah 5:16 | MÍMỌ́ | Romu 7:12 |
| Deuteronomi 32:4 | ÒDODO | Romu 7 :12 |
| Matteu 5:48 | PÍPÉ | Orin Dafidi19:7 |
| 1 Johannu 4:8 | ÌFẸ́ | Romu 13:10 |
| Eksodu 9:27 | ÒDODO | Orin Dafidi19:7 |
| Deuteronomi 32:4 | ÒTÍTỌ́ | Orin Dafidi 119:142,151 |
| 1 Johannu 3:3 | MÍMỌ́ | Orin Dafidi 19:8 |
| Johannu 4:24 | ẸMÍ | Romu 7:14 |
| Malaki 3:6 | ÀÌLÈYÍPADÀ | Matteu 5:18 |
| Genesisi 21:23 | AYÉRAYÉ | Orin Dafidi 111:7,8 |

Òfin Ọlọrun kò se e yípadà, nítori tí ó jẹ́ àwòrán ìwà Rẹ̀. Ọ̀rọ̀ ológo nínú Ìwé Mímọ́ to se apejúwe Ọlọrun, tún n se apejúwe òfin Rẹ̀. Ó fin Ọlọrun Jẹ́ Ìwà Rẹ̀ ní kikọ. Kò se e ṣe mọ́ lati yi òfin Ọlọrun padà, tàbí kí a yi Ọlọrun funrarẹ̀ padà.

**2.** Ní ìgbékalẹ̀ ti Bibeli, kínni ẹ̀ṣẹ̀?

**1 Johannu 3:4**
Ẹnikẹni tí ó bá ndẹ́ṣẹ̀ o nrú òfin pẹ̀lú, nítorí ẹ̀ṣẹ̀ ni _________ òfin.

**Romu 3:20**
Nítorí pé nípa iṣẹ́ òfin, a kì yíò dá ẹnikẹni láre níwájú rẹ̀ : nítorí nípa _________ ni ìmọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ti wá.

Àkíyèsí : Ẹ̀ṣù kò fẹ́ràn òfin nítorí tí o mọ̀ wípé nipasẹ rẹ̀ ni a fi nmọ̀ wípé a nílò Olùgbàlà kúrò lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀. Romu 4:15 sọ wípé : ' Nitori òfin nsiṣẹ ìbínú : sùgbọ́n níbití òfin kò ba sí, irufin kò sí níbẹ̀.' Òfin kò le gba ẹnikẹni là, sùgbọ́n o n fi pípé Ọlọrun ati àìpé àwa ènìyàn hàn wa.



**3.** Òfin wo ni **1 Johannu 3:4** ntọka si?

**Romu 7:7**
Njẹ́ àwa ó ha ti wí ? Òfin ha iṣe ẹ̀ṣẹ̀ bí ? kí a ma ri. Sùgbọ́n emi kò ti _________ ẹ̀ṣẹ̀.

Àkíyèsí: Òfin mẹwa Ọlọrun ló sọ wípé, 'Ìwọ kò gbọdọ̀ sojúkòkòrò.' Nítori náà rìré Òfin Mẹwa Ọlọrun kọjá, èyí tí Ó fi ìka Rẹ̀ kọ (Eksodu 31:18; 32:16), jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀. Irú ẹ̀ṣẹ̀ tí o wù kí ẹnikẹni le è dá, ni idalẹbi kan tàbí ju bẹ́ẹ̀ lọ nbẹ fun nínú Òfin Mẹwa. Nítorí ìdí èyí ni Òfin Ọlọrun fi njẹ́ 'Gbòòrò' (Orin Dafidi 119:96) ati 'pípé' (Orin Dafidi 19:7). Ó kó 'gbogbo ojuṣe ènìyàn' já (Oniwaasu 12:13). Bí a bá ti mọ ara wa ní ẹlẹ́ṣẹ̀, a o wa Olùgbàlà. Ní paapa jùlọ, ẹ̀ṣù kò fẹ́ràn òfin, nítorí pé òfin ma nrán wa létí lati wá Jesu, kí Ó lè dáríjì wá.

**4.** Njẹ́ Jesu pa Òfin Mọ́?

**Johannu 15:10**
Bí ẹnyin ba pa òfin mi mọ́, ẹ o dúró nínú ìfẹ́ mi ; gẹ́gẹ́ bi emi ti ______ òfin Baba mi mọ́, tí mò sì dúró nínú ìfẹ́ rẹ̀.

Àkíyèsí: Nítòótọ́ Jesu pa Òfin Mẹwa mọ gẹ́gẹ́ bi apẹẹre fún wa (1 Peteru 2:21)

**5.** Àwọn melo ló ti dẹ́ṣẹ̀?

**Romu 3:23**
_________ ènìyàn li o sa ti sẹ̀, ti nwọn sì kùnà ogo Ọlọrun.

**6.** Kinni ìjìyà tó wà nínú gbígbé ìgbé ayé ẹ̀ṣẹ̀?

**Romu 6:23**
Nítorí _______ li èrè ẹ̀ṣẹ̀; sùgbọ́n ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ Ọlọrun ni ìyè tí kò nípẹ̀kun nínú Kristi Jesu Oluwa wa.

Àkíyèsí: Bí ó ba jẹ́ wìpé òfin Ọlọrun le ṣe é yípadà ni, kò li le e pọn dandan fun Jesu lati ku lori igi agbélebú. Nípasẹ̀ òtítọ́ wípé Jesu san gbèsè ẹ̀ṣẹ̀, tí O sì kú, jẹ́ ẹ̀rí idaniójú wípé òfin kò le ṣe é yípadà.

**7.** Àwọn kan sọ wípé Òfin Mẹwa kò jẹ́ dandan fún àwọn kristiani ti mẹ́jẹ̀mú titun. Kinni Jesu sọ nipa èyí?

**Matteu 19:17**
Ó sì wí fun un pe, Eeṣe tí iwọ fi pè mí li ẹni rere ? Ẹni rere kan kò sí bíkoṣe ẹnikan, eyini li Ọlọrun: ṣùgbọ́n bí ìwọ ba nfẹ wọ ibi ìyè, ______ òfin mọ́.

**Johannu 14:15**
Bí ẹnyin bá fẹ́ràn mi, ẹ o ______ òfin mi mọ́.

**Ifihan 22:14**
Ìbùkún ni fun àwọn ti _______ òfin rẹ̀ mọ, ki nwọn kí o le ni anfani lati wà sí ibi igi ìyè náà, ati kí nwọn kí o lè gba àwọn ẹnubodè wọ inú ìlú náà.

**Ifihan 14:12**
Nihin ni sùúrù àwọn ènìyàn mímọ́ gbé wà; àwọn tí _______ òfin Ọlọrun ati ìgbàgbọ́ Jesu mọ́.

Àkíyèsí: Májẹ̀mú titun kọ́ wa li ọ̀nà tó já gaara wípé àwọn ènìyàn Ọlọrun gbọ́dọ̀ pa òfin Rẹ̀ mọ́. gbogbo wa mọ̀ wípé ayé wà nínú isoro nlá loni nítorí wípé ọ̀pọ̀lọpọ̀ li kò rò wípé, o se pàtàkì lati gbọ́ràn si òfin Ọlọrun mọ́. Bibeli sọ nipa ìgbà ti wa yìí wípé :

'Oluwa, o to àkókò fun ọ lati sisẹ : nítorí ti nwon ti sọ òfin rẹ di òfo. Orin Dafidi 119:126.

**8.** Báwo li o ṣe rọrùn tó lati pa òfin mọ́?

**Romu 8:3,4**
Nítorí ohun tí òfin kò le ṣe, bí o ti jẹ́ alàìlera nitori ara, Ọlọrun rán Ọmọ oun tikararẹ̀ li àwòrán ara ẹ̀ṣẹ̀, ati bi ẹbọ fún ẹ̀ṣẹ̀, o si da ẹ̀ṣẹ̀ lẹbi ninu ara, kí a le mú òdodo òfin ṣẹ _________ _________, tí kò rìn nipa ti ara, bíkòṣe nípa ti Ẹmi.

**Filippi 1:6**
Ohun kan yi sa da mi lójú, pé ẹniti ó ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere _________ _________, yíò se àṣepé rẹ̀ títí fi di ọjọ́ Jesu Kristi.

**Filippi 4:13**
Emi le ṣe ohun gbogbo nínú _________ ẹniti nfi agbara fun mi.

Àkíyèsí: Nígbàtí ẹnikan ba di atunbi, Jesu Kristi nípasẹ̀ Ẹmi Mímọ́ yíò wọ inú ẹni bẹ́ẹ̀, yíò sì tún mú kí ìgbọràn rọrùn li ọ̀nà ìyanu fun un.

**9.** Kíni májẹ̀mú láíláí, àti wípé kinni ó mú kó kùnàn?

**Deuteronomi 4:13**
Ó sì sọ majẹ̀mú rẹ̀ fun nyin, tí o palaṣẹ fun nyin lati ṣe, àní _________ _________ ni ; ó sì kọ wọn sara walaa òkúta meji.

**Heberu 8:8**
Nítorí tí ó rí _________ lara _________, o wípé, kíyèsí i, ọjọ́ mbò, li Oluwa wí, tí èmi o ba ilé Isreali ati ilé Juda da májẹ̀mú titun.

**10.** Lórí òfin wo li májẹ̀mú titun dúró lé lórí?

**Heberu 8:10**
Nítorí èyí ni májẹ̀mú tí èmi o ba ilé Isreali dá lẹhin ọjọ́ wọnni, li Oluwa wi ; Èmi o fi _________ mi sí inú wọn, èmi o si kọ wọn sí _________ wọn : èmi o sì ma a jẹ́ Ọlọrun fún wọn, nwọn o sì maa jẹ́ ènìyàn fún mi.

Àkíyèsí: Májẹ̀mú mejeeji jẹ́ ìfìmọ̀ sọ̀kan laarin Ọlọrun ati àwọn ènìyàn Rẹ̀. Májẹ̀mú láíláí kùnàn nítorí wípé ó dúró lórí ìlérí tí o li àbùkù àti iṣẹ́ ènìyàn.

**Eksodu 24:7**
Ó sì mú ìwé májẹ̀mú ni, ó sí ka a li etí àwọn ènìyàn : nwọn sì wípé, gbogbo èyítí Oluwa wi li àwa o se, àwa o sì gbọran.

Májẹ̀mú titun yege nítorí tí o jẹ́ òfin Ọlọrun tí a kọ sí ọkàn, tí o si dúró lórí ìlérí Jesu ati agbára tí Ó fi nsiṣẹ́ ìyanu.

**Heberu 8:10**
Èmi o fi òfin mi sì inú wọn, emi o si kọ wọn sí ọkan w ọn.

Ìsẹ̀dá ènìyàn yíò yípadà, yíò sì ri siṣe ìfẹ́ Ọlọrun gẹ́gẹ́ bi ohun ìgbádùn. Ẹ kíyesi wípé májẹ̀mú titun dúro lórí òfin kanan, sùgbọ́n tí a kọ sí ibi to yàtọ̀ (ọkàn) ó sì dúró lórí ìlérí tó dara jù (ó jẹ́ ti Ọlọrun)

**11.** Njẹ́ gbígbé lábẹ́ oore ọ̀fẹ́, nípa ìgbàgbọ́, kò sọ pípa òfin Ọlọrun mọ́ di ohun tí kò se pàtàkì bí?

**Romu 6:15**
Njẹ́ kinni ? kí àwa kí o ha maa dẹ́ṣẹ̀ (ki a rú òfin Ọlọrun), nítori tí àwa kò sí lábẹ́ òfin, bíkose lábẹ́ oore ọ̀fẹ́ ? _________ a ma _________.



**Romu 3:31**
Àwa ha nsọ òfin dasán nípa ìgbàgbọ́ bi ? kí a ma ri: sùgbọ́n a nfi _________ _________.

Àkíyèsí: Àwọn tí a ti dáríjì nípasẹ̀ Jesu nítorí pé wọn nrú òfin Rẹ̀, tun si nsiyèméjì pé bóyá ojuṣe àwọn tún li lati ma a gbọràn si òfin tàbí rárá. Wọn nro ìbùkún ìdáríjì Rẹ̀ tí wọn rí gbà, wọn tún fẹ́ kí àwọn le e ma a tẹle Jesu pẹ̀lù ayọ̀ ju àwọn ẹlòmíràn lọ.

**12.** Sé nìpa pípa òfin mọ́ ni a fi ngba àwọn ènìyàn là bí?

**Efesu 2:8,9**
Nítorí _________ _________ li a ti fi gba nyin là nípa ìgbàgbọ́ ; ati eyini ki ise ti ẹnyin tikarayin: ẹ̀bùn Ọlọrun ni.

Àkíyèsí: Kò sí ẹnikan ti a ngbàlà nípà pípa òfin mọ́. Gbogbo ènìyàn la gbàlà nípa iṣẹ́ ìyanu oore ọ̀fẹ́ ti Ọlọrun. Sùgbọ́n àwọn tí a gbàlà tí a sì tùnbí, pẹ̀lú oore ọ́fẹ̀ Jesu wọn yíò fẹ́ lati ma a pa òfin Rẹ̀ mọ́, lati ma a fi ẹ̀mí ìmoore wọn hàn sí Ọlọrun.

**Johannu 14:15**
Bí ẹnyin ba fẹ́ràn mi, ẹ o pa òfin mi mọ́.

**13.** Kílo ma nrú ènìyàn sókè lati gbọ̀ràn sí òfin Ọlọrun?

**Romu 13:10**
Ìfẹ́ ki iṣe ohun búburu sí ọmọnikeji rẹ̀ : nítorí náà ______ li àkójá òfin.

**Matteu 22:37-39**
Jesu sì wí fun un pé, kí ìwọ kí o fi gbogbo ______ rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inú rẹ, fẹ́ Oluwa Ọlọrun rẹ, Ẹ́yí li ekinni ati òfin nla, Ekeji sì dàbi rẹ̀, Ìwọ fẹ́ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ.

**1 Johannu 5:3**
Nítorí èyí ni ______ Ọlọrun, pé kí àwa kí o pa òfin rẹ̀ mọ́ : òfin rẹ̀ ko sì nira.

Àkíyèsí: Ìfẹ́ jẹ́ ohun tó lágbára tó ma nruni sókè. Òfin mẹrin àkọ́kọ́ dá lórí ojúse mi sí Ọlọrun, tí mo ba fẹ́ràn Rẹ̀, gbígbọ́ràn sí àwọn òfin pẹ̀lú yíò jẹ́ ayọ̀ tàbí ìgbádùn fun mi. Mẹ́fà tó gbẹ̀hìn gbàjúmọ́ ojúse sí awọn ènìyàn. Bí mo bá fẹ́ràn àwọn ènìyàn nítòótọ́, mi o li fẹ se ohun tí yíò pa wọn lára sí wọn.

**14.** Njẹ́ mo le e jẹ́ Kristiani tòòtọ́ laipa òfin Rẹ̀ mọ́?

**1 Johannu 2:3,4**
Nípa èyí li a sì mọ̀ pé àwa mọ ọn, bí awa ba ______ òfin rẹ̀ mọ́, Ẹniti o bá wípé, emi mọ ọn, tí kò sì pa òfin rẹ̀ mọ́, ______ ni, otítọ́ kò sì sù nínú rẹ̀.

**15.** Sé àwọn kan nínú òfin májẹ̀mú láíláí kò yẹ fún àwọn Kristiani mọ́?

**Efesu 2:15**
O si ti fi òpin si ọ̀ta nì ninú ara rẹ̀, ani si òfin aṣẹ wọnni ti mbẹ nínú _______; ki o le fi àwọn mejeji dá ẹni titun kan nínú ara rẹ̀, kí o si se ìlàjà.

Àkíyèsí: Bẹẹni, àwọn òfin ti ìlànà alufa ati ti ẹbọ sisun li a ti paré nítori tí wọn n sapẹre Kristi. (Kolosse 2:13-17). O mú wọn sẹ gẹ́gẹ́ bi ọ̀dọ-agutan Ọlọrun.

**16.** Àwọn wo li èṣù korira ní pàtó ?

**Ifihan 12:17**
Dragoni náà sì bínú gidigidi sí _________ náà, o si lọ ba àwọn irú ọmọ rẹ̀ ìyókù jagun, ti nwọn ________ òfin Ọlọrun ọ́, tí nwọn si di ẹ̀rí Jesu Kristi mú.



Àkíyèsí: Èṣù korira àwọn ìjọ ìkẹhìn ayé àti pé inú rẹ̀ nru si wọn, àwọn to npa òfin Ọlọrun mọ tí wọn sì nkọ́ àwọn ènìyàn wípé agbara nlá kan wà to le e sọ ẹlẹ́ṣẹ̀ di àyànfẹ́.

**17.** Kinin àwọn èrè ologo tó wà nínú ki a pa òfin Ọlọrun mọ?

**Johannu 15:11**
Nkan wọnyi ni mo ti sọ fun nyin, kí _______ mi kí o le wà nínú nyin, ati ki ayọ̀ nyin kí o le kún.

**Owe 29:18**
Nibiti ìran woli kò si, ènìyàn a yapa, sùgbọ́n _________ ni fun ẹniti o pa òfin mọ.

**Orin Dafidi 119:165**
_________ púpọ̀ li àwọn tí o fẹ́ òfin rẹ̀ ní : kò sì sí ohun ìkọ̀sẹ̀ fún wọn.

Àkíyèsí: Ìdùnú, ayọ̀, alaafíà, ati igbé ayé ọ̀pọ̀ ma nwá sí ọ̀dọ̀ àwọn tó ngbọ́ràn sí òfin Ọlọrun. Abájọ tí Dafidi fi wípé òfin Ọlọrun ju wúrà dáradára púpọ̀ lọ. (Orin Dafidi 19:10).

# Èsì Rẹ

N jẹ o fẹ lati ni ibaṣepọ̀ pẹlu Jesu èyí tí yíò yọri sí wípé iwọ náà jẹ ọkan nínú awọn alayọ olugbọran ọmọ Rẹ̀?

ÌDÁHÙN: ______________

# Àfikún

Ipele yìí pèsè awọn ìròhìn àfikún fun kikẹkọ tẹsíwajú.

## Ìbasepọ Tó Wà Laarin Apẹẹrẹ Bibeli Àti Jesu

Púpọ̀ nínú awọn akíkanjú to wà ninu Bibeli li wọn jẹ irú àti àpẹẹrẹ Jesu. Mose, Josefu, Dafidi ati Solomoni li ayé wọn jẹ́ òjìjí ayé àti iṣẹ́-ìránṣẹ́ Jesu, ní àwọn ikorita kọ̀ọkan nínú ìrìn àjò ayé wọn. Ìbámu tó wà laarin ìrírí wọn, ngbiyànjú lati ṣe iranlọwọ fun aráyé lati mọ̀ Jesu gẹ́gẹ́ bi Ọmọ Ọlọrun.

Ìrírí Danieli nípa òfin ati àwọn kiniun, jẹ́ àpẹẹrẹ kan níti ìbáramu ti ẹ̀mí. Ṣe àkíyèsí àwọn ìbámu wọnyi :

- Awọn olórí li Medo-Persia wọn fẹ lati yọ Danieli kúrò li ipò nítori ti wọn njowú ajọsepọ tó dán mọran laarin oun ati ọba. Danieli 6:3 sọ wípé : "... ọba si gbèrò lati fi i ṣe olórí gbogbo ijọba."
- Awọn olórí Medo-Persia tún tẹle Danieli kakiri pẹlu ete lati mu kí o ma sọ tabi se ohun ti kò dara (Danieli 6:4). Li ìgbà ayé Jesu awọn olorin ẹ̀sìn náà ran amí lati ma a sọ Jesu, ni iretí lati mu Un pe O n sọ tabi se ohun ti ko dara pẹlú (Luku 20:19,20).
- Awọn ọ̀tá Danieli kò ri ohun kankan, nitori ìdí éyí wọn pète lati mu erongba wọn ṣẹ (Danieli 6:5-9). Bẹẹ pẹlú, awọn olorin alufa ati awọn amofin gbimọ pọ̀ pẹlu Judasi Iskariotu lati dẹkun fun Jesu (Luku 22:26). Ni gbẹhin, Pilatu jẹwọ wípé oun ko ri ẹsun kan si Jesu (Johannu 18:4).
- Lẹ́hin tì a ti sọ Danieli sinu iho kìkiun, a yi okuta kan sí ojú iho náà, ati oruka èdìdí awọn ijoye (Danieli 6:16,17). A gbé Jesu pẹlu sinu iboji ti a fi okuta nlá di ẹnu ọna iboji náà, nwọn fi si fi èdìdí di okuta náà (Matteu 27:58-60,65,66).
- Danieli pẹlu Jesu jẹ alaimọkan ati wípé wọn si jade kúrò ninu ẹ̀wọ̀n wọn láàyè (Danieli 6:23; Marku 16:5,6).

Wo bóyá o sì tun lee ri ibasepọ kankan laarin ìgbé ayé Bibeli ati ti igbé ayé Jesu.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP6.indd 2 12/6/12 11:07 AM